# ÒÒGÙN ALÁÀBÒ

## Lo òògùn rẹ̀ lát[wà ní àlàáfíà

**Òògún aláàbò ní ó máa ń báàbò bo ènìyàn lọ́wọ́ àìsàn**

## KÍN NI ÌDÍ TÍ MO FÍ NÍLÒ ÒÒGÙN ALÁÀBÒ?

Ní ìlú Amẹ́ríkà, ọ̀pọ̀ àwọn àìsàn tí ó dojúkọ àwọn ènìyàn ní ó ti ń lọ . Ọkan nínú ìdí pàtàkì ní lílo àwọn òògùn aláàbò. Òògùn aláàbò máa ń dènà àwọn àìsàn tí ó lè máa ràn láti ara ẹnikan sí èkejì.Bí obá ti gba ìwọn òogùn tí o nílò, o ti dáàbò bo ara rẹ àti àwọn olólùfk rẹ lọ́wọ́ àìsàn.

## BÁWO NI ÒÒG]UN ALÁÀBÒ ṢE Ń ṢIṢẸ́?

A ṣe òògùn aláàbò láti ara fáírọ́ọ̀sì (kòkòrò àrùn) kan náà tí ó sokùnfà àisan náà. Kòkòrò àrùn tí a lò láti ṣe òògùn aláàbò lè ti kú tàbí kí ó má lágbára mọ́. Kó níí jẹ́ kí o ṣàìsàn Dípò èyí, yóó ṣerànwọ̀ láti dojú ìjà kọ kòkòrò àrùn àti àwọn àìsàn tí wọ́n fà.

## TAA LÓ NÍLÒ ÒÒGÙN ALÁÀBÒ?



## ǸJẸ́ Ó NÍ ÀYỌRÍSÍ BURÚKÚ BÍ?

Àwọn ènìyàn mìíràn máa ń ní àyọrísí burúkú lẹ́yìn lílo òògùn wọn. Èyí sì gbọ́dọ̀ lọ lẹ́yìn ọjọ́ kan sí méjì.



Ara ríro/Ojú pípọ́n　Ara yíyún　Ibà

Àwọn ènìyàn mìíràn kì í ṣábà ní àyọrísí burúkú lẹ́yìn lílo òògùn wọn. Lọ́pọ̀ ìgbà, wọ́n máa ń wáyé lẹ́yìn ìṣẹ́jú díẹ̀ tàbí wákàtí díẹ̀ tí wọ́n lo òògùn wọn.



Àìlèmí dáadáa　Rírẹ̀　Ara híhún/Yíyún　Ọ̀fun wíwú

## ÒÒGÙN ALÁÀBÒ WO NI MO NÍLÒ?

Àtẹ tí ó wà ní apá kejì ń ṣàfihàn ìwọn òògùn tí àgbà àti ọmọdé nílò. Àgbà tí kò gba ìwọn òògùn yìí pé lọmọdé lè gbá ìwọn tó pọ̀. Bá dọ́kíta rẹ sọ̀rọ̀ láti mọ ìwọn òògùn tí o nílò.

**Fún àlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́, kàn sí www.vaccines.gov**

**Orúkọ dọ́kíta mi:**

**Nọ́ńbà fóònù dọ́kíta mi:**


Àṣẹ Àdálò © 2015, MAGNUS, Walnut, CA

# Lo òògùn rẹ lát[wà ní àlàáfíà

**Kán sí dókítà rẹ fún àyẹ̀wò kí o sì gbà ò]ogùn tí o nílò.**

Ìwọ̀n òògùn tí o nílò ní a sàmì sí nísàlẹ̀ yìí: ____________________ ____________________
(Orúkọ) (Ọjọ́-orí)

Ìgbà tí wàá padà wá: ____________ ____________ (ààrọ̀/ọ̀sán) ____________
(Ọjọ́) (Àkókò) (Ọjọ́ ibí)

| Ìwọ̀n òògùn tí o nílò | Kín ni orúkọ tí à ń pè é? | Taa ló nílò rẹ? | | | Ìrú àìsàn wo ní òògùn yìí máa ń wò? | Kín ni àìsàn náà ń fà? |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | Ọmọdé* Níkan | Ọmọdé & Àgbà | Àgbà nìkan | | |
| ☐ | DTaP tàbí Td/Tdap | | X | | Bèlúbèlú | Ìbà, ọ́fun dídùn òtútù |
| | | | | | Tátánọ́ọ̀sì | Pajápajá àti àìlèmí dáadáa tàbí gbígbé nǹkan mì |
| | | | | | Ikọ́ fére | Ìkọ tó ń dúni àti àìlèmí dáadáa, àìlèjẹun àti àìlèmu dáadáa |
| ☐ | Ogìnnìtìn | | X | | Ogìnnìtìn | Àrùn imú |
| ☐ | HepA | | X | | Hepatitis A | Ẹyà àìsàn ẹ̀dò |
| ☐ | HepB | | X | | Hepatitis B | Ẹyà àìsàn ẹ̀dò |
| ☐ | Hib | | X | | Haemophilus influenza type b | Àìsàn tòsí ọpọlọ àti ogòóró ẹ̀yìn |
| ☐ | HPV | | X | | Jẹjẹrẹ ẹnu ilé ọmọ | Ẹya àìsàn jẹjẹrẹ obìnrin |
| | | | | | Àwọn kókó tó so ojú abẹ | Ẹ́yà àìsàn tí ó lè tànkálẹ̀ nípa ìbálòpọ̀ |
| ☐ | IPV | X | | | Rọmọlápa-rọmọlẹ́sẹ̀ | Ara tí kò ṣeé gbé tàbí lọ́pọ̀ ìgbà , àìlèmí |
| ☐ | MCV4 | | X | | Meningococcal | Àìsàn tòsí ọpọlọ àti ogòóró ẹ̀yìn |
| ☐ | MMR | | X | | Àìsàn ìta, | Ibà, kòkòrò ara, òfinkìn, ikọ́ |
| | | | | | Kókó | Ibà, ẹ̀fórí àti kí àbala kan tí itọ́ tí ń wá ní ẹnu wú |
| | | | | | Rùbélà | Ibà, inú wíwú, àti kòkòrò ara |
| ☐ | PVC | | X | | Pneumococcal | Àìsàn ẹ̀dọ̀ |
| ☐ | RV | X | | | Rotavirus | Ìbà, èébì, ìgbẹ́ gbuuru |
| ☐ | Varicella | | | | Àìsàn Ìta | Kòkòrò ní gbogbo ara |
| ☐ | Ẹ́gbèsì | | | X | Ẹ́gbèsì | Kòkòro ara tó ń dunni pẹ̀lú ọyún |

** Ọmọdé láti ọjọ́ – orí 0 sí 18*

**Dáàbò bó ìwọ àti àwọn olólùfẹ́ rẹ Gba ìwọn òògùn rẹ**


Àṣẹ Àdálò © 2015, MAGNUS, Walnut, CA